AWỌN OHUN PATAKI
NINU IWE ỌSẸ YI
Oju iwe 1
Ijẹsa kolọ'da
Oju iwe 1
Alaga yi sabẹwo
Oju iwe 2
Fa Ọgbọn yọ
Oju iwe 3
Ọ.ọ nbi ọrọ

Oju iwe 4
Obati Jesu yẹwo
Oju iwe 5
Ta kokoro ipinlẹ
Oju iwe 5
Ẹgbẹ Agbẹ
Oju iwe 5
Ibusọ moto
Oju iwe 7
Ṣọ ke tẹ

# IRAWỌ ★ OBOKUN

Vol 4 No 144 ILESHA MONDAY JULY 11 1955. IYE OWO: TỌRỌ

# IJỌBA ILẸSA PE IPADE AṢOJU GBOGBO ẸGBẸ ATI ONIṢOWO ILU



ỌLỌLA J.O. FADAHUNSI

On ni alaga fun Ijọba gbogbo ilẹ Ijẹṣa' On ati alabojuto eto iṣẹ ijọba yio ṣe abẹwo ọna agbegbe afa (bridge), ile kotu; ile ti awọn ọmọde ti nkọwe ati ile ti wọn ti ngbegbogi lati 19 si 23 oṣu yi.

## ALAGA YIO ṢE ABẸWO IṢẸ AGBEGBE

Lati ọjọ keje oṣu yi ni wọn ti fiwe sọwọ si gbogbo awọn ijọba akamọ kọkan ni agbegbe pe Alaga ijọba Ilẹ Ijẹṣa, Ọlọla J. O. Fadahunsi yio ṣe abẹwo iṣẹ ni agbegbe.

Abẹwo na bẹrẹ lati ọjọ kọkandinlogun oṣu yi si ọjọ kẹtalelogun. Awọn ohun ti Alaga na nlọ bẹwo ni awọn ọna moto agbegbe ile awọn kotu gbogbo, ile ti wọn ti ngbegbogi, awọn ile ti wọn ti nkọwe ati bẹ lọ titi.

Alabojuto eto iṣẹ ijọba Ijẹṣa Ọgbẹni E. Kọlawọle yio pẹlu Alaga ṣe gbogbo abẹwo na. Eto irin ajo na lọ bayi:-

Ni agogo mẹwa owurọ ọjọ kọkandinlogun oṣu yi, agbegbe Oshun Local Council; agogo mejila ọjọ na—agbegbe Ibokun Local Council Agogo kan abọ ọsan ọjọ na—agbegbe Kiriji Local Council; Ni agogo mẹta abọ ọsan ọjọ kanna—agbegbe Okebode Local Council ati Moroko Local Council.

Ogunjọ oṣu yi ni agogo mẹwa owurọ—agbegbe Ijẹbu-Jẹṣa Local Council; agogo mejila—agbegbe Esa-Oke Local Council; Agogo mẹta ọsan—agbegbe Aiyetoro Local Council; Agogo mẹrin—agbegbe Itagun Local Council; Agogo marun abọ irọlẹ—agbegbe Ibodi Local Council.

Ọjọkọkanlelogun oṣu yi ni agogo mẹwa owurọ—agbegbe Ipetu-Jẹṣa Local Council; agogo mejila—agbegbe Erin Local Council; agogo kan abọ ọsan—agbegbe Aiyepeju Local Council; agogo mẹta ọsan—agbegbe Isaobi Local Council.

Ọjọ kejilelogun oṣu yi ni agogo mẹwa owurọ—awọn agbegbe Ifẹwara ati Ilupeju Local Council: agogo mejila abọ ọsan—agbegbe Iwara Local Council,. Ni agogo mẹta ọsan—agbegbe Irẹpọdun Local Council.

Ọjọkẹtalelogun oṣu yi ni agogo mẹwa owurọ—agbegbe Ifẹlodun Local Council; ni agogo mejila abọ ọsan—Aiyegunlẹ Local Council.



KANSẸLO J. M. OBE

On na wa ninu igbimọ ijọba to ṣeto ipade aṣoju gbogbo ilu. Wọn yio fi ọpọlọpọ eto fun idagba soke ilu ti wọn ti nṣe niwaju pade na loni.

## KO SI IJẸṢA NINU IPINLẸ TI YIO L'ỌDA

Ni ọjọ ti Minista eleto iṣẹ Ọlọla E. A. Babalọla wa si omi ẹrọ ni Ileṣa lo sọpe igbimọ to nṣeto tita ati rira koko ti fi ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun mẹrin (£4,000,000) silẹ fun atunṣe ọna ni Ẹkun Iwọ Orun Naijiria.

Lẹhin na awọn eleto iṣẹ ọna bẹ ipinlẹ Ijẹṣa wo, awọn aṣoju ijọba Ileṣa si fun wọn ni akọsilẹ awọn ọna to fẹ atunṣe ati ti wọn fẹ ki wọn fọda si ni ipinlẹ Ijẹṣa.

Ṣugbọn ni ọjọ kẹtalelogun oṣu to kọja, ọkan ninu awọn eleto iṣẹ ọna na, Ọgbẹni Alfred Rewane ka oruko awọn ipinlẹ ti wọn yio fowo na ṣọda si fun igbimọ eto iṣẹ ti Ado Ekiti. Ko si ipinlẹ Ijẹṣa ninu awọn to ka.

Awọn ibiti o ni awọn fẹ ṣe ati iyẹ maili ti wọn fẹ fọda si nibẹ ni wọnyi:—

Ipinlẹ Badagry, maili mẹtadinlogun; Ipinlẹ Ikẹja, maili mẹrindinlogbọn; Ipinlẹ Ẹgba, maili mẹrindinlogun; Ipinlẹ Rẹmọ, maili mẹrindinlogun; Ipinlẹ Ijẹbu, maili mẹtadinlogbọn; Ipinlẹ Ọshun, maili mẹrinlelogbọn; Ipinlẹ Ifẹ, maili mọkanlelogun Ipinlẹ Ibadan, maili mọkanlelogun; Ipinlẹ Ondo, maili mẹrindinlogbọn; Ipinlẹ Ọwọ maili mejidinlogbọn; Ipinlẹ Ekiti, ọgọrun mail ati meje ati abọ.

Ko sọ pe wọn yio ṣe ẹyọ maili kan lọda ni Ipinlẹ Ijẹṣa.

Wọn fi ye wọn nigbati wọn bẹ Ipinlẹ Ijẹṣa wo pe maili mẹrinla pere ni Ijọba Ẹkun Iwọ Orun Naijẹria ntọju ni gbogbo ọna ilẹ Ijẹṣa.

## IJỌBA PE IPADE GBOGBO AṢOJU ILU

Lati oṣu to kọja ni a ti gbọ nibi pataki pe Ijọba Ileṣa ti ngbimọ lati pe ipade gbogbo aṣoju ilu.

Ni ọsẹ to kọja ni a gbọ pe wọn ti pe ipade na si ọjọ kọkanla oṣu yi (loni gan a). wọn ti fi iwe sọwọ si gbogbo ẹgbẹ ilu lati fi aṣoju meji-meji ranṣẹ.

Pataki ohun ti a gbọ pe wọn fẹ ba wọn sọrọ le lori ni ọrọ nipa omi ẹlẹrọ, ina alatanmọlẹ, ibusọ moto, ọja titun. a si rope wọn yio sọrọ lori ọja alanapọ ti ẹgbẹ obirin NCNC kọwe si ijọba nipa rẹ.



ỌGBẸNI O. WILLIAMS

On jẹ ọkan ninu awọn alakoso iṣẹ awọn ẹgbẹ agbẹ. Akọle olotu tọka bi awọn ọmọ ẹgbẹ agbẹ ṣe sọ pe ẹdinwo ni ẹgbẹ wọn nraja toribẹ wọn nta ọja wọn fun awọn oniṣowo Ifẹ.

**POLOWO OJA**

**Re, Ki o si fi**

**EDUN OKAN RE**

**Sinu**

**IRAWO OBOKUN**

## Change Of Name.

I formerly known and called David Oni Awẹ of N 52, Abituri Street, Ilesha, wish to be known and called Iburaimoh Oni Bakare from July 11, 1955.

All previous documents bearing my former name remain valid.

IBURAIMOH O. BAKARE.

## ILESHA ARCHDEACONRY
## Elementary Training College.

The Entrance Examination to this new College for men which opens at Ilesha in January, 1955, will be held on Wednesday 24th August, 1956 at the following Centres:

**St. John's School Iloro Ilesha**
**Auglican Central School, Ifẹ.**
**St. Mark's School, Offa.**

Applicants should have taught for at least one year by December, 1955. Applications for forms should be accompanied by a fee of 3/- payable to the Secretary Ilesha Archdeaconry Board, P. O. Box 16, Ilesha, not later than August, 11th when entries close. Candidates who had applied for a Grade III course at St. Luke's College Ibadan need not re-apply.

**J. A. Akinyemi**
Secretary
Ilesha Archdeaconry Board.

# FA ỌGBỌN YỌ

## ESI SI ỌRỌ JULIUS ỌLA

(Lati ọwọ Isaac Adewusi, G 5 Isare Ileṣa.)

Alatiṣe funra rẹ lo ma nmọ atiṣe ara rẹ. Alatiṣe ni aya pupọ, o bi ọmọ, ninu awọn ọmọ rẹ a ri eyiti o ti dagba dada. Kama ri, oju Alatiṣe lọ, o di akura.

Lẹhin eyi, Alatiṣe ro ọrọ na titi, lo wa pin awọn iyawo rẹ ti wọn wa lọwọ ibimọ fun awọn ọmọ rẹ. Lẹhin ọdun diẹ ti Alatiṣe ti ri idanwo yi, o lọ joko sinu ọgba rẹ. Ẹiyẹ adaba kan fo si abẹ ijoko rẹ. Asec, aṣa lo nle adaba na bọ, bẹni adaba na nsọ bayi fun Alatiṣe wipe tio ba le gba on la kuro ni ọwọ ewu aṣa yi, on yio jẹki o kuro ni akura.

Bẹni aṣa na si sọ bayi fun Alatiṣe wipe bi o ba le jẹki on gbe adaba yi lati pajẹ on yio mu oju rẹ to ti fọ yi la. Ọran yi wa di riro fun Alatiṣe.

Nigbati o ya, Alatiṣe ran enia si gbogbo awọn aya rẹ tio ti pin fun awọn ọmọ rẹ wipe ki gbogbo wọn wa. Nigbati wọn de, o ko ọrọ na o ro fun gbogbo wọn. Awọn aya rẹ si dahun bayi wipe ma jẹki aṣa yi gbe adaba na lọ nitoripe ti ko ba ti gbe adaba na, adaba yio jẹki o kuro ni akura, iwọ yio si maṣe ọkọ idi nipe awọn obirin ko fẹ fi ọkọ wọn silẹ tẹlẹtẹlẹ.

Alatiṣe loma mọ atiṣe ara rẹ o, esi yi ko tẹ a'atiṣe lọrun rara, o si tun ranṣẹ pe awọn ọmọ, rẹ o ko ẹjọ yi o ro fun wọn. Awọn ọmọ rẹ si fun Alatiṣe lesi pe ki o jẹ ki Aṣa gbe adaba na nitoripe bi aṣa ba gbe adaba yi oju rẹ yio la, Nitoripe bi a ba gbe onjẹ fun ọ iwọ yio ri, bi awọn ọrẹ rẹ ba wa ki ọ iwọ yio ri wọn, bi o ba si fẹ lọ si oko iwọ yio riran lati lọ, bi o ba si fẹ lọ ode iwọ yio lọ funrarẹ.

Alatiṣe ni on gbọ ṣugbọn ọrọ yi ko tẹ lọrun rara. O wa nronu ara rẹ gẹgẹ bi on yio ti ṣe ọran na. Lẹhin eyi Alatiṣe wọ ile o gbe ọkan ninu awọn adiẹ rẹ fun aṣa na, lẹhin igbati aṣa ti jẹ adiẹ na tan ni aṣa yi ba, ti iyẹ rẹ gba alatiṣe loju, oju alatiṣe si la, lẹhin eyi aṣa na lọ. Bẹni alatiṣe ba pe adaba wipe iwọ ko fẹ lọ mọ ni, bẹni adaba na sọ bayi pe aṣa na ti lọ bi, Alatiṣe sọ fun adaba na pe aṣa na ti lọ o. Bẹni adaba yi si jade. Lilọ ti o lọ tan ni alatiṣe kuro ni akura.

Dajudaju awa ri nihin yi pe Alatiṣe fi ọgbọn yọ ara rẹ. Abọ mi reo Olotu Irawọ Obokun, ẹbẹ mi si Oluwa ni pe ki o ma fiwa silẹ sinu idanwo. amin ati amin.

---

(Lati Ọwọ Kunle Aderogba, A 28, Adeti, Ileṣa)

Olotu Irawọ Obokun, inu mi yio dun ti ẹ ba le gba mi laye lati fesi si itan Ọgbẹni Julius Aluko to jade ninu Irawọ Obokun laipẹ.

Mo gba Ọgbẹni Julius ni yanju lati wa ọmọ adiẹ miran ki o fun Ọmọba lati fifun Aṣa na dipo ọmọ adiẹ akọkọ to sa wa si ọdọ wipe ki o gba on la lọwọ Aṣa. Lẹhin igbati o ba fun Aṣa ni ọmọ adiẹ miran yi tan ki o wa bẹ lati mu ileri rẹ ṣẹ wipe on yio jẹ ko di ọkọ obirin; ẹhinna ki [illegible] adiẹ akọkọ ki o bẹ ki o mu ileri rẹ ṣẹ ki o le la oju rẹ nitori on tigba silẹ lọwọ Aṣa:

Esi re o, Olotu – Mo dupẹ.

---

## AKIYESI.

A ṣe ifilọ yi fun ẹnyin onkawe ati onibara wa pe lati igba yi lọ ki ẹnikẹni maṣe fi orukọ ọsiṣẹ san owo fun ile-ẹrọ itẹ'we wa bi ko ṣe pe Olotu tabi Manager IJESHA PRESS LIMITED. A si fẹ ki o ye yin kerede pe ki i ṣe ẹbi Olotu tabi Manager bi a ba ri ẹniti owo rẹ ba sọ nu nipa aikasi alaye yi o.

ALABOJUTO

---

## ADUGBO AKỌLỌṢỌ NFẸ ATUNṢE

(Lati Ọwọ Dandy Ola Kareem, Oke-Eṣọ. Ileṣa)

Mo bẹ Olotu ko gba mi laye lati sọ ọrọ kekere yi.

Ẹ jọwọ ẹnyin Oṣelu Ijẹṣa ati ẹnyin ọjọgbọn ilu Ileṣa pe ki ẹ ba wa mura si adugbo Akọlọṣọ, ko dabi ẹgbẹrẹ.

Ati papa ẹnyin ogunagbongbo to wa ninu ẹgbẹ Akukọ ati ẹnyin ogunagbongbo to wa ninu ẹgbẹ Ọpẹ, ki ẹ ba wa mura si atunṣe adugbo wa na o.

Ẹ jọwọ o ẹnyin ara ilu Ileṣa ati ẹnyin oṣelu inu rẹ pe ki ẹ ba wa mura si itọju adugbo yi.

---

## IFILỌ FUN AWỌN ARA ẸRINMỌ

(Lati Ọwọ S. T. Ogundele, 68, Agbeni, Ibadan)

Inu mi yio dun bi Olotu Irawọ Obokun ba le gba mi laye lati ba awọn ọmọ Ẹrinmọ to wa lẹhin odi sọrọ.

Ipade jẹ ohun kan pataki, Ilu ti ko tobi to Ẹrinmọ nṣe ipade ni ẹhin odi. Ẹ wo Ileṣa, wọn nṣe ipade ni ẹhin odi, bẹni ọmọ Iloko, bẹni ọmọ Erin. Mo bẹ awọn ọmọ Ẹrinmọ to wa ni ilu Akure, eyiti o jẹ ibusọ mẹtala si Ibadan, mo bẹ Joseph Otokola, Floku Fọlami, Michael Olowoyẹye, Isaac Ajọrọ, Ezekiel Olowoyọ, o fẹ ki wọn ma ṣe ipade ni Ibadan pẹlu ara Lalupọn.

Mo bẹ Paul Ekemọde, Jonah Ṣajuku ati Noah Ọlọmọ, a fẹ ki wọn ma ṣe ipade ni ilu Ibadan. Ati ara Akinyẹle a bẹ Timothy Logunde ati Mattew Logunde.

Mo bẹ gbogbo awọn ti mo kọ silẹ yi pe a nfẹ ki wọn ma ṣe ipade ni Ibadan, mo gba wọn niyanju pe ki wọn ma ṣe da bi awọn to ma nsọrọ to lodi si ilu Ẹrinmọ, ni aimọ pe bi Ẹrinmọ dara, bi ko dara o kan wọn. Mo fẹ fi ye wọn pe ẹniti o ba lo di si ilu rẹ ẹranko ni. Mo ma ngbọ lẹnu awọn ti ko mọ nkankan ti wọn ma nsọrọ lodi si Ẹrinmọ. Ọpọlọpọ awọn to nsọrọ odi si Ẹrinmọ wọnyi, a le ri ẹniti o ti kọ le bi ojule mẹfa toke todo ni nu wọn. Sibẹsibẹ wọn nsọrọ to lodi si ilu Ẹrinmọ pe ilu Ẹrinmọ ko dara. Iru enia bẹ jẹ olobu enia bi adiẹ to ye ẹyin, nigbati o pa to ku ẹyin kan ṣoṣo, Olowo rẹ nsọpe o ti yan obu.

Gbogbo ẹnyin ọkawe Irawọ Obokun Ọlọrun ma jẹ ki a yan obu. Ọbẹ ti ko ba ni iyọ ni nyan obu. Mo bẹ ẹnyin onigbagbọ ti ẹ wa lẹhin odi, mo fẹ ki ẹ ma ṣe ipade, emi ko fẹ ki ẹ lodi si orilẹ ede yin. Ẹ si le ri ka ninu Bibeli pe ki a ma ṣe lodi si orilẹ ede ilu wa.

---



ỌGBNI M. D. ỌLỌWẸ

On ni Alaga fun Ẹgbẹ Agbẹ (Co-operative Societies) Ileṣa. Akọle Olotu wa ọsẹ yi tọka si pe ọpọlọpọ ọmọ Ẹgbẹ na olaju fun onisọwo Ipinlẹ miran toripe ẹdinwo ni iẹgbọ Agbẹ.

## Ẹ FI IBUSỌ MOTỌ SI ITA BALOGUN

(Bẹrẹ ni oju iwe 5)

awọn onisowo aṣọ, awn ati awọn ohun mẹrẹmẹrẹ miran bẹbẹ provisions)

Itu awọn ile be yio je eyiti a npe ni (Lock up stores) bọ gẹgẹ bi o ti wa ni ilu ibomiran gbogbo ti o je ilu ọlaju itu awọn ile ṣọ to ṣe i tilẹku mọ lalalẹ.

Gbogbo re yio je hihaya fun awọn onisọ wọnyi. Owo ti o ba si ti be wa yio kọja si apo ijọba Ilẹṣa lati ma fi ṣatunṣe ti wọn na si oja ra.

Awọn onibuṣọ moto ra yio ma ṣanwo iwọle ni ibuṣọ moto na pẹlu.

Awọn akan mejeji yi, ibuṣọ moto (motor park) ati oja gbogbogbo (Central Market) koni lati jẹ ki ara wọn rara gẹgẹbi mo ti ma nri ni ilu ibomiran gbogbo.

Lati ibuṣọ moto nitosi onitita ati ọnitita oja kole sa rara, nitoripe awọn oro ti o nrọja moto ni opọlọpọ ma nba wọlu.

IBUṢỌ MOTỌ SIWAJU

Ti o ba ṣe owo ni ko iti si to lopo ijọba Ibile lati ṣe awọn eto wọnyi lakoko yi, nwọn si le ṣe ibuṣọ moto.

Gẹgẹ bi aba mi yi, ki a fi ti oja ṣe igba miran, ka ṣe atunṣe popo si oja Ọba ti nwọn nna nsinyi, ka si sa lọ lọ bẹ lati ti owo yio fi wa to lati ṣe okan yoku. Ṣugbọn ki a ni lokan wipe ilosi ibuṣọ moto ni wọn yio ṣe si.

Nipa dida aba wọnyi, ẹlomiran le ma sọ wipe kini ṣe to jẹ Ita-balogun ni emi o kọ iwe yi si lẹhin mọ; koje ọran iyan ti a ba run le ri ibomiran ti o tun mọ oju ọna gbogbogbo (Main Road) ti o si je tosi ara wọn nitori gẹgẹ bi Loya ati Adajọ ni awọn nkan mejeji yi ri, ti nwọn ko gbọdọ ya ara wọn.

Ẹ TỌJU IRAWỌ OBOKUN

Ekẹta ọrọ mi ni wipe mo bẹ gbogbo awọn ọmọ Ijẹṣa ti o jẹ oṣelu ati onkowe Irohin, ati awọn Olotu ati akọbọjuto ile iṣẹ itẹwe Irawọ Obokun, ki wọn ki o gbiyanju lati wa ọna miran ṣe Irawọ Obokun ati idagbasoke iṣẹ Ijẹṣa Press, ju ebobu ati isọkuso si ara wa lọ ninu iwe onira fun ile Ijẹṣa ti nṣe Irawọ Obokun.

Dipo eleyi, ẹ jẹki a gbiyanju lati jẹki iṣẹ rere iwe Irawọ Obokun ki o di mimọ fun awọn onile eut miran ti o ṣi wa ka, lati gba awọn Akọwe agbodegba (News Reporter), ki o ma lọ kakiri awọn ilu agbegbe bi Oṣogbo, Ede, Ogbomọṣọ, Ikirun ati awọn ilu tẹọṣ lati ma gba irohin ati ẹdun wọn ṣinu Irawọ Obokun lati ma tẹ si etigbọ Ijọba ati gbogbo aiye.

Nipa bẹ ko ni jepe Ijẹṣa nikan ni yio ma ni ipo diduro lati ma ra Irawọ Obokun ni idalẹ bikoṣe gbogbo awọn ilu miran to jepe wọn yio mọ wipe irohin ilu wọn na ma nbẹ ninu rẹ nigba gbogbo.

Nipa bayi ipolowo oja ninu iwe onire na yio ma ni ilọsiwaju ju wipe ki o sa jepe ọrọ nipa ẹgbẹ oṣelu tabi awọn ọrọ nipa ile Ijẹṣa nikan ni yio ma jẹ kikọ ninu iwe na. Tabi ibiti iṣu ku, ti nwọn bẹ si obẹ, gẹgẹ bi iyawo gbigbe, ọmọ lorukọ, tabi oku sisin ti ko le jẹ nkan iwuri fun awọn okawe wa ni idalẹ ti ko mọ ẹniti o ku, tabi ti a sin oyawo tabi adugbo ibiti o ngbe.

Ẹ jẹki a ṣe ohun to bo jumu ti awọn ara okere yio ri, ti nwọn yio ma gba wipe ọpọgbọn wa ni ilu tabi ile Ijẹṣa.

Nigunlẹ ọrọ mi, mo bẹ gbogbo awọn oṣelu wa, Ọba ati awọn Ijoye, lọkunrin ati lobinrin ati awọn Olotu ati Alabojuto ile iṣẹ Irawọ Obokun, ki nwọn fi oju agba wapo lati dide si awọn ohun ti yio ma mu ki ogo Ijẹṣa tunbọ ma tan siwaju laisi ikunsinu laarin ẹnikan si ẹnikeji.

Ki a gbiyanju lati gbe gbogbo awọn aba ati imọran yi yẹwo fun ọmuṣẹ lọna ti o bojumu; ati feke gbogbo rẹ, lati gbe iwe irohin ologo wa (West African Vanguard) dide lẹkan si ki a si fi owọ so ọwọ pẹlu iṣẹ lati ri wipe iku ko tun ri gbe ẹ mọ.

Oluwa Ọlọrun Olodumare ati Obokun ti o da ilẹ Ijẹṣa koni jẹ ko baje lowọ nyin. Ire lẹ o, ma ri, ti ẹ o si ma ṣe o.



ỌGBẸNI ALAKE ABANIKANNDA

On na je ọkan ninu awọn onisowo moto ati epo pataki larin ilu. Ọrọ lori ọrọ ero, ina lẹntiriki, ibuṣọ moto ati oja titun le suyọ ti pade ti aṣoju ẹgbẹ gbogbo ilu ni yio lọ loni.

---

## ẸGBẸ KO ṢE ẸGBẸ

(Lati ọwọ ọgbẹni A.O. Fadegbe A.M.I. Iroye)

Ohun ti mo fẹ sọrọ le lori nipe, nwọn ṣegbẹ nwọn ko ṣegbẹ ko to ohun ti jọ je mu ija wa. Awa ti a jẹ ẹniti nwo wọn niran, a fẹhinti a nwo iṣẹ wọn ṣugbọn ohun ti a nri ni wipe ki nwọn maṣe di ẹru to wuwo le wa lori.

Mo rope ti ọkunrin ba ni iyawo meji ọkọkan ni yio ma sun ti wọn. Bi o ba sun ti iyale; to ba kan iyawo iyale ko gbọdọ binu rara. Bi a tiṣe nri iwe awọn oṣelu ka yi dabi ẹni pe Iyale fẹ jowu ni yọju nigbana. Nigbati oyinbo si da duro ko si ẹgbẹ kan ti o bere lowọ wọn.

Ko si yẹ ki a ma jowu ara wa, awọn ti o ba wa lori Alefa, ẹ jẹki nwọn ma ba eto wọn lọ. Awa ti a dẹ nvan wọn, a ki ṣe ọbọ. Nitori obirin ti ọbẹ rẹ ba dun on ni ọkọ faramọ.

Nitori eyini nipe, nwọn ko iti ṣe ẹgbẹ nigbati oyinbo ti wa nlana Railway nibi, ko si ẹgbẹ kan to mi nigba miran.

Lẹhinna, a nṣore a ko si mọ ọkan ninu gbogbo ore eto yi. Nitori na ki ẹ maṣe ṣọ wa di ọlọrun lile, ọbẹ to ba dun on lo nfa olowo rẹ mọra. Nitori irohin ti a ngbọ ati eyiti a nrika ninu Irawọ Obokun, a nfi wọn ara wọn wo, o nyawa lẹnu. Mo dupẹ olotu ati Irawọ Obokun, ẹo tun ma ri ọwọ mi nigba miran.

---

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWỌ OBOKUN"

OJU EWE KINI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inṣi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 7s. | " " " |

OJU EWE KEJI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 5s. | fun inṣi kan. |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | " " " |
| Igba | 26—52 | 4s. | " " " |

OJU EWE KẸTA

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun inṣi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | " " " |

OJU EWE KẸJỌ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | " " |
| Igba | 26—52 | 5s. | " " " |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JE OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE "E".

## ẸGBA TI JESU NA RO

(Bẹrẹ ninu iwe 4)

(Minista) ati ẹnyin Ẹ,bẹ atunluṣe nibi gbogbo, ẹ ronu ki ẹ gba ọrọ yi ro, ki ẹ si dide si iranlọwọ ati atunṣe Ijọ Ọlọrun lonilẹ ede ati agbaiye. Ẹ gba ti Jesu na ro" (Heb. 3 1)

Ẹ DA WỌN LỌLA

Gbogbo awọn ti a ba ti sọ di Minista ni ẹnyin Ijọba ma ada lọla Orisirisi ohun elo ni ẹ ma gbe fun wọn lati ma rin ka gbogbo ilu. Elomiran kẹkẹ, omiran Alupupu omiran mọ tọ lati le ma lọ si ibiti o jina ti o yẹ ki iṣẹ ijọba ki o de, ti ko si ṣe iṣẹ lati fẹsẹ rin de bẹ. Jesu Oluwa sọ fun awọn ọmọ ẹhin rẹ pe, "Ẹnyin o si ma ṣe ẹleri mi ni Jerusalẹmu, ni Samaria, ni Judia ati titi o fi de opin aiye" (Iṣe Aps. 1:8)

Ọrọ yi yẹ awọn orilẹ ede miran ni ilu Oyinbo to bẹ ti awọn fi ṣe iranlọwọ owo fun awọn oniṣẹ Ọlọrun lati wa si orilẹ ede wa. Ki iṣẹ bẹ n kan, igbati awọn ba de ilu wa nibi, gbogbo wọn lo ni mọtọ ti awọn nṣa kikiri lati ma mu ihin rere lọ si ilẹ okunkun. Ki iṣẹ awọn lo ra mọto yẹn; ṣẹni a gbe fun wọn lọfẹ.

Ẹ ko ri bi awọn orilẹ ede na ti ṣe da awọn iranṣẹ Ọlọrun lọla bayi?

Opọ ilu lo wa lorilẹ ede wa yi (NIGERIA) ti ihin rere Kristi ko i de bẹ, ti wọn ko si ti mọ oru kọ ọmọ Ọlọrun ti a npe ni JESU. Ọrọ awọn Ijọ Ọlọrun ni itara eyi jọ ijkan lati de awọn ilu bẹ, ṣugbọn owe awọn agba kan sọ pe, "A ri ẹleru o ku ẹnito ma gbe", Awọn ojiṣẹ Ọlọrun ko le lọ si ira awọn ilu bawọnyi mbẹ, ṣugbọn kini yio gbe wọn dọhun, tani yio si ma ṣonwo owo fun wọn.

A! ẹnyin ijọba ẹ ranti Ọlọrun ti o fi nyin sipo ọla, ki ẹ si ṣe iranlọwọ fun iṣẹ Ọlọrun, gbogbo ọna ti ẹ le gba ṣe iranlọwọ fun Ijọ Ọlọrun, ati fun itẹsiwaju ihin rere si ilẹ lorisirisi ona nimu aiye lati; "Ẹ GBA A RO

Ninu iwe orin C. M. S. No 1, ẹsẹ 2 sọ fun ni bayi pe, "Ro gbogbo ọjọ ti o ti ṣofo. Bẹrẹ si rere iṣe loni"——

Nitorina, ẹnyin Ijọba ti Oluwa fi sipo iranṣẹ Ọlọrun ni gbogbo nyin, ohun ti o yẹ ki ẹ ti ma ṣe ni eyi ṣugbọn ẹ ti fi silẹ laiṣe. Ẹ ranti gbogbo ọjọ ti ẹ ti fi ṣofo, ki ẹ bẹrẹ si rere iṣe fun Ijọ Ọlọrun; ati fun awọn ojiṣẹ rẹ pẹlu.

"Ẹ gba ti Jesu na ro o".

Ẹnyin oniglogbo ẹlẹgbẹ mi; agba ati ọmọde, ẹnyin iranṣẹ Ọlọrun ẹlẹgbẹ mi, ewe ati agba, abọ mi re o. Ẹnyin na ẹ gba ọrọ yi ro laria ara ẹnyin o. Ọjọ ko fẹra ku o. Laipẹ ko tun ma gburo mi. Nitori " Jesu atẹnumọran ki jona. "Emi ko le ṣe alaiṣe iṣẹ Ẹniti o ran mi nigbati iṣe ọsan oru mbọ nigbati ẹnikan ko le ṣiṣẹ (Jehn 9-4

## Ẹ WỌLẸ KI Ẹ TO BẸ

(Lati Ọwọ Ọlọla Ọlagija Ikẹran)

Ọ Ninu si sọrọ lori ọrọ ti Alafin, ijọla Ọlọtẹju, ọkan ninu awọn aṣaju ni igbimọ Iyofin nla, mọ ọrọ rẹ si awọn Ọba ati awọn mẹkunnu ti Ẹkun Iwọ Orun Naijiria Ọrọ rẹ lọ bayi:-

Mo bẹ Ijọba ti Ẹkun Iwọ Orun Naijiria lati tẹ eti gbọ si gba awọn mẹkunnu lori ọrọ Alafin pe ko pada si Ọyọ.

Bi o ba jẹ pe ijọba Action Group fẹ ṣiṣẹ ni itẹlọrun awọn mẹkunnu ti o dibo fun wọn, emi ko ri idi ti wọn fi ni lati ma tunka mọ ọrọ ti ko muna doko, Loni wọn a sọpe aya Alafin lẹ, lọla wọn a sọpe Alafin kọ lati lo asiko tiademilu rẹ ni Ilẹ. Bi o tan di ọtunla wọn a sọpe Alafin faramọ Ẹgbẹ NCEC

Emi ka eleyi si ọrọ aigbọn.

Ti o ba ṣe pe ijọba Action Group fẹ ṣiṣẹ laini eru, kiniṣe ti wọn ko faramọ iyọnu iwadi ti Ọgbẹni Lloyd ṣe ki wọn si kilọ fun Alafin nipa alafia ati ilọkanbalẹ ilu rẹ

Gbogbo awọn to nnaga lati gba ijọba yio ti ma ronu ohun ti yio ṣẹlẹ si wọn bi o ba jẹpe bi ijọba enia dudu yio ti ma ṣe ni wọn nṣe si Alafin yi.

Emi nfi eleyi han awọn ọmọ Action Group pe kundekunde ti wọn ngbiyanju lati ṣe de ọdun 1956 dabi igbati Aja ngbo. O dabi igbati enia npe aja lati wa jẹun ti oluware si yọ kuro dani. Nje awọn ọmọ Action Group yio le gbiyanju lati fun ijọba ara ẹni ni gbeyẹwo di.?

Emi gba wipe awọn Action Group ni ẹrọ ti o ma nsọrọ irọ fun awọn akọwe oni kundekunde wọn. Wọn ti da ogunlọgọ aṣurọ jẹnu sode lati ma ṣe kundekunde ọdun 1956 silẹ. Nwọn ti gbagbe pe awọn ko i ti lọ aba wọn ara wọn nu.

Nwọn tan gbogbo awọn ọba lati ran wọn lọwọ, ṣugbọn loni ogunlọgọ awọn Ọba na lo nkigbe fun iranlọwọ pe "E jẹki Alafin pada si Ọyọ" Ṣugbọn ko si idakun ti o le fun wọn ni ireti titi di isinsiyi. Ti o ba jẹ pe gbogbo awọn Ọba ti Ẹkun Iwọ Orun Naijiria ni A. G emi ko ri idi ti ijọba wọn ko lati gbọ ohun wọn lasiko.

Eyi jẹ ẹkọ ati iriri fun awọn Ọba to ba nro pe ẹni tobi si ijọba na. Alafin Ọba to jẹ ẹkan ninu awọn Oba nla di ẹniti wọn nii kakiri lairo ti awọn ẹlẹgbẹ rẹ lo nbẹbẹ fun. Ohun to nṣẹlẹ si Ajai loni le ṣẹlẹ si Dada lọla.

Ti o ba jẹpe otitọ ni a fẹ lati ni eyọ ijọba kan ni Ẹkun Iwọ ọrun tabi eyọ Naijiria kan, o yẹ ki a jina si eto iṣelu bi ti ADAN. O ki a a si fẹran ara wa

## AKIYESI PATAKI

Eyi ni lati sọ fun gbogbo awọn to nkọwe sinu Irawọ Obokun pe lati asiko yi lọ a ko ni faye gba iwe ẹnikẹni ti ṣe ata ko ẹnikẹni tabi ẹgbẹkẹgbẹ. Ṣugbọn aye wa fun ẹnikẹni lati sọ ọrọ lori eto ati iṣẹ ẹgbẹ tirẹ laipa ẹnikẹni lara:

ALABOJUTO



KANSẸLỌ M. A. K. ẸSỌ

On pẹlu awọn Kanselo ti ijọba Ijẹṣa titun yan fun abojuto igbo Ijẹṣa ni ibiti wọn ti sagbe pelu Ondo. A gbọ pe idiwọ ti wa fun awọn to nji igi Ijẹṣa bẹ sibẹ.

## AKIYESI

FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGBẸ NCNC-ẸGBẸ AKUKỌ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ NCNC mọ pe ipade ọjọ mẹjọ-mẹjọ ti a nse ni Wednesday ko yi pada; nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede.

## ANNOUNCEMENT

This is to announce to the general public that after the 25th of July 1955 the Office of the Ijesha Press Ltd will be removed from B 110 Okesha Street, Ilesha to the work-shop, B 149 Okesha Street, Ilesha.

Therefore all communications should be directed to:-

Ijesha Press Ltd.
P. O. Box 23,
B 149 Okesha Street
ILESHA.

## IFILỌ PATAKI

### Fun Awọn Onibara Wa

A bẹ olukuluku awọn Onibara wa ti wọn jẹ IJESHA PRESS ni igbese ki wọn ki o mu ni ọkunkundun lati jẹki igbese ti wọn jẹ ki o tete de ọwọ Olotu Iṣẹ yi ni ipari osu June titi di ipari ọsẹ kini ninu oṣu July 1955, ki a ba le ni igbende nla ninu apakan iṣẹ yi ti o ti ku;

AKỌLE OLOTU

## IPADE GBOGBO AṢOJU ILU

Awọn agbalagba lo ma npa lowe wipe bi omi titun ba ti de, ẹja titun ni lati ko wọ. Ni gba kini lati igbati Ilẹ Ijẹṣa tide Ijẹṣa, awọn aṣoju kọkan larin Ẹgbẹ gbajumọ ilu, onisowo ilu, Lori—ọmọ ilu, Ẹgbẹ oni-motọ, Ẹgbẹ awa motọ, Ẹgbẹ agbero, Ẹgbẹ a-ya-motọ lo (Charterers), Ẹgbẹ oni tita ati oni rira, lọrọ kan, awọn aṣoju gbogbo ilu Ileṣa yio jẹ ipe Ijọba wọn loni. Ẹgbẹ iṣelu yi loni ijọba na tabi ti Ẹgbẹ iṣelu yẹn kọ. ki i ṣe ohun ti o kan awa ti Irawọ Obokun, ṣugbọn iwuri nla lo jẹ fun wa lati ripe ijọba kan ronu si pe o yẹ lati pe aṣoju awọn to fi wọn sipo ba sọrọ.

Awọn ọrọ ti a gbọ pe ijọba fi sọkan lati ba awọn aṣoju na sọ ṣe pataki to bẹ ti a fi rope a yẹ ki a bẹ gbogbo awọn ti wọn ba pe lati mu anfani na lo Fun akiyesi bi aṣigbọ ti nlọ lori owo mi, bẹni arebajọ nlọ lori owo ina al-tanmọlẹ. Ẹniti o ba ka iwe wa toni yio ri ọpọlọpọ ilọrọwerọ lori ibiti o yẹ ibusọ motọ ati ọja titun. Lẹhinna ogunlọgọ enia lo ti nreti ohun ti ijọba yio ṣe lori aba ọja alanapọ ti Ẹgbẹ awọn Obirin da. Gbogbo awọn nkan wọnyi ni awọn to ba lọ si ipade na lẹtọ lati bere ọrọ le tabi sọrọ lori rẹ.

Ẹbẹ wa si awọn to nlọ si ipade na loni nipe ki wọn maṣe jẹ ki Ijọba to pe ipa e na kabamọ; Ṣugbọn ki wọn fun wọn ni igboya lati ma lẹmi pipe ira ipade bẹ nigbagbogbo nipa ifọkanbalẹ gbọ ọrọ, nipa ifesi pẹlu ẹmi ifẹ, nipa ifarabalẹ, nipa ihuwa ọmọluwabi, ju gbogbo rẹ lọ, nipa si sọrọ pẹlu ẹni ifẹ ilu yatọ si ife Ẹgbẹ-ko-ṣẹgbẹ iṣelu. Ṣise awọn nkan wọnyi yio si ma tọka fun awọn oniyemeji pe awọn ọmọ Adulawọ le ṣeto Ijọba wọn funra wọn, ati fun anfani ara wọn".

## ADUGBO OKOGBA NFẸ ABOJUTO

(Lati Ọwọ Dandy Ọla Kareem, Oke-Ẹsọ, Ileṣa)

Jọwọ Olotu gba mi laye lati sọ ẹdun ọkan mi yi.

O jẹ ẹdun ọkan fun mi lati ripe adugbo Orogba lo lọ sẹhin ju ninu gbogbo adugbo Ileṣa. Ẹ jọwọ ẹnyin oselu Ileṣa, ki ẹ ba wa bojuto adugbo wa yi o.

Ekini:- Adugbo na ko ni oju ọna to dara, 2. Koni omi ẹrọ; 3.Koni pako itọkasi adugbo gẹgẹ bi ti awọn toku. Njẹ eleyi ba oju mu bayi ẹnyin ọmọ Obokun?

A tun bẹ ẹnyin oṣelu adugbo wa, ki ẹ ba wa ran awọn oṣelu leti lati ba wa bojuto dugbo wa yi o.


# WANTED.

Applications are Invited from Suitable Candidates to fill the post of a Secretary / Treasurer for Aiyegunlẹ Local Council.

**Qualification — Class IV**

Certificated Teachers in the Council Area who apply as a part time worker will also be considered.

The successful candidate will be required to produce two Bondsmen.

Applications marked "Secretary / Treasurer" should be submited to:—

The Chairman, /
Aiyegunlẹ Local Coun .
P. O. Box 16,
ILESHA.



# ILESHA GRAMMAR SCHOOL

## Aionian Group Of Secondary School

## Entrance Examination 1955.

The Entrance Examination for admission of boys to Class One Secondary in January 1956 will be held on Wednesday 7th September 1955 in the School Hall.

Application for forms should be through Headmaster with examination fees of 2/6d; No individual form will be sold out.

Entry closes August 7th 1955:

All forms must be returned by August 21st 1955.

**J. A. Akinyemi**
Principal.




KANSẸLỌ M. I. EKUNDARE

On jẹ ọkan ninu awọn to ṣeto ijọba Ileṣa loni. Ijọba na ti fiwe sode lati pe awọn aṣoju ilu si ipade loni gan. Akọle Olstu bẹ awọ o nlọ si ipade na lati farabalẹ gbọ ọrọ.

## E KA NIPA IJOBA YIN

Wọn ni "bi egungun ẹni ba njo daradara, ori ẹni a ma ya" Irawọ Obokun lero wipe yio jẹ idunnu olukuluku lati ma ri irohin itẹsiwaju ka nipa igbimọ-ijọba akamọ tirẹ; nitoribẹ, a ti nṣe orişirişi atunṣe ni imurasilẹ lati ma ripe irohin njade ni ọsọsẹ nipa gbogbo awọn ijọba na.

Inu wa yio dun bi ẹnyin ọkawe wa ati aṣoju wa bi fọwọsowọpọ pẹlu wa lati ripe iṣẹ na rọrun ni ṣiṣe

Ọna ti ẹ fi le ran wa lọwọ nipe:-

A fẹ Aṣoju (Agent) ni ilu kọkan.

A fẹ aṣoju si ni Ileṣa.
A fẹ awọn ti yio ma fun wa ni irohin pipe,
A fẹ awọn Ọkawe kun awọn Ọkawe wa.

A fẹ ki awọn ti o mura tan lati ma ba wa ṣowo jẹ awọn ti yio ma sanwo lasiko.

Nitorina a nfẹ aṣoju ti yio ma fun wa ni irohin ati ti yio ma ta Irawọ Obokun ni awọn ilu wọnyi:- Ieṣa, Ibodi, Iperindo, Imẹsi Ile, Muroko, Itagun, Ipole, Igangan, Isẹ, Odo, Ilọba, Iwara, Erin Odo, Erin Oke, Ẹsa odo, New Ikeji, Old Ikeji, Isaobi, Ijẹbujeṣa, Etiọni, Ilerin, Ifẹ, Ibadan, Ọffa, Ikirun, Iragbiji.

## E FI IROHIN IPADE IGBIMO YIN

SỌWỌ FUN TITẸ JADE NINU

# Irawo Obokun

Printed and Published by Ijesha Press Ltd., B149 Okesha Street, Ilesha 11 - 7 - 55